# IṢẸ TI A RÁN SI AWỌN ỌDỌ

**Oniwasu 11:9, 10; 12:1-14**

**ẸKỌ 378 ---FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia" (Oniwasu 12:13).**

### Oniwaasu

"Mo fẹ lọ dán an wo funra mi," ni gbolohun ọ̀rọ ti a ti maa n gbọ́ ti ọpọlọpọ ọ̀dọ́ maa n sọ. Nipa bẹẹ awọn ọ̀dọ́ maa n lodi si imọran awọn alufaa, awọn olukọ Ile-Ẹkọ Ọjọ Isinmi, awọn oṣiṣẹ Ihinrere ati awọn obi; wọn a si yan ọna ti ara wọn wọn a si maa duu lati wá ayọ ati itẹlọrun ninu faaji ayé.

Ninu Iwe ti a n pe ni "Oniwasu," ni a ti ri iwaasu kan ti ọkunrin ti o gbọ́n ju lọ ni gbogbo ayé wà. Oniwaasu kilọ fun ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin pe Ọlọrun yoo mú olukuluku awọn to huwa aiwa-bi-Ọlọrun wa si idajọ ni ọjọ kan. O sọ fun awọn ọdọmọde pe ki wọn maa yọ̀ ni igba ewe wọn, ṣugbọn ki wọn kiyesara lati ri i pe ohun ti wọn n ṣe dun mọ Ọlọrun ninu. Bi bẹẹ kọ, ki o ranti pe "nitori nkan wọnyi Ọlọrun yio mu ọ wá si idajọ."

### Idanwo

Awọn ti kò ba ni igbala ki i ni agbara lati doju ija kọ idanwo. Wọn maa n fara fun igbadun ti wọn ro pe kò lewu, lai pẹ lọ titi wọn a ba ara wọn ninu dida ẹ̀ṣẹ ti o buru ju bi ọjọ ti n gori ọjọ. "Olukuluku ni a ndanwò, nigbati a ba ti ọwọ́ ifẹkufẹ ara rẹ̀ fá a lọ ti a si tàn a jẹ. Njẹ, ifẹkufẹ na nigbati o ba lóyun, a bi ẹ̀ṣẹ: ati ẹ̀ṣẹ na nigbati o ba si dagba tan, a bi ikú" (Jakọbu 1:14, 15).

Satani le tan ọ jẹ lati lọ wo sinima, lati fa eefin taba diẹ simu, bi o tilẹ jẹ lẹẹkan ṣoṣo, tabi lati dá awọn ẹ̀ṣẹ miiran. Bi Ẹjẹ Jesu kò ba si ninu ọkàn rẹ, iwọ le ju ọwọ silẹ fun un: bi Satani ba si fi ọwọ rẹ̀ le igbesi-ayé rẹ, iwọ ki i tun ṣe oluwa ara rẹ mọ́ ṣugbọn o ti fi ori le ọna iparun ayeraye.

### Fifun Irugbin ati Ikore

Ni igba kan ọkunrin kan ṣe akiyesi eso oat kan ti o hù jade ti o si n dagba, o tu ilẹ yi i ká, o si n ṣọ ọ titi o fi gbó. O ja ìdì oat naa o si ka iye eso ti o wà ninu rẹ̀. Ẹgbẹrin eso ni o jade lati inu ẹyọ eso kan ṣoṣo ti ijọ́si. Nigba naa ni o fi inu ṣiro rẹ̀ pe bi oun ba gbin gbogbo ẹgbẹrin eso wọnni ni akoko ifurugbin, oun ni lati ri to ogoji oṣuwọn ni akoko ikore. Bi oun ba si gbin gbogbo ogoji oṣuwọn oun ni lati ri to ẹgbẹjọ oṣuwọn. Bi oun ba si gbin ẹgbẹjọ oṣuwọn eso naa, lai pẹ lọ titi oun le mu gbogbo ilẹ ayé kun fun oat, gbogbo wọn yoo si jẹ eyi ti o jade lati inu ẹyọ horo oat kan ṣoṣo.

Njẹ iwọ tilẹ ti i ronu lọ sinu Ọgba Edẹni ri, eyi ti o wà niwọn bi ẹgbaata ọdun sẹyin, nigba ti Adamu ati Efa fun irugbin ẹ̀ṣẹ kekere kan ṣoṣo, ti o dagba ti o si di ilọpo-ilọpo titi di oni to bẹẹ ti gbogbo ayé kun fun ẹ̀ṣẹ ati ibanujẹ? "Ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká" (Galatia 6:7).

### Gbigbagbe Ọlọrun

O jẹ iwa were lati maa lo igbesi-ayé wa bi ẹni pe ọjọ oni nikan ṣá ni o ṣe danindanin. Otitọ ni pe akoko igba ewe ti ọ̀dọ́ kò ni ojuṣe kankan lati boju to ni igba rẹ̀ ti o dara ju lọ boya. Ṣugbọn sibẹ a kò gbọdọ lo igba ọmọde ati igba ọ̀dọ́ fun kiki igbadun nikan, ni Sọlomọni, Oniwaasu wi. O ni a gbọdọ ranti Ẹlẹda wa ni ọjọ ewe.

Iwe iṣiro gẹgẹ bi akọsilẹ fi hàn pe meje ninu ọmọ mẹjọ ni o maa n sá kuro ni ile-isin ati Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi ki wọn to di ọmọ ọdun mẹẹdogun. Awọn akọnilẹkọọ ti orilẹ-ède Amẹrika sọ pe awọn ọmọde lati ọdun mẹsan-an si ọdun mejila ni ọjọ oni maa n fi aibalẹ ara hàn, wọn si n ni ibẹru ati wahala pupọ ju ti atẹyinwa. Awọn iwe iroyin n sọ nipa awọn ọmọde ti n dá ọran ti o bani lẹru gidigidi; iwa abuku awọn ọ̀dọ́ ti di ọran ti n fẹ abojuto gidigidi. Akọwe-sinu-iwe-iroyin kan ti iwe iroyin ti a n pà ni New York Times sọ lai pẹ yii nigba ti o n sọ nipa bi ohun gbogbo ti ri ni orilẹ-ède Amẹrika pe: "O dabi ẹni pe kò si ẹni ti o le sọ bi o ti ri gan an tabi bi o ti ṣe ri bẹẹ, ṣugbọn olukuluku ni o mọ pe nnkan naa kò rọgbọ."

Ni tootọ, nnkankan ti ṣẹlẹ. Awọn eniyan gbọdọ ranti Ẹlẹda wọn ni ọjọ ewe wọn, ki wọn wá Oluwa, ki a si gbà wọn là kuro ninu ẹ̀ṣẹ; lẹyin naa ki wọn lepa àya funfun ki wọn si ni i, eyi ti a n pè ni isọdimimọ́. Awọn ọ̀dọ́mọkunrin ati ọ̀dọ́mọbinrin paapaa le wá Oluwa ki wọn si ni awọn iriri wọnyii, gẹgẹ bi wọn ti le ni ifi Ẹmi Mimọ́ wọni pẹlu ni igbesi-ayé wọn. Nigba naa pẹlu ọpọ adura ati kika Ọrọ Ọlọrun wọn le gbé igbesi-ayé ododo, igbesi-ayé Onigbagbọ́ ki wọn si jẹ irànwọ lati mú ki awọn ẹlomiran ri igbala.

Sọlomọni mọ ohun ti oun n sọ nigba ti o ranṣẹ yii si awọn ọ̀dọ́ awọn ọ̀rọ rẹ̀ si ti ipa imisi Ẹmi Mimọ́ wá. Yoo dara ki olukuluku ọ̀dọ́mọde le fiye si wọn. Sọlomọni jẹ ẹni ti o ni ọrọ̀ pupọ o si ni ọpọlọpọ iṣura ayé yii ni arọwọto rẹ̀. O jẹ igbadun faaji, ọlá, ọrọ̀. O ni ohun ti o dara ju lọ ni ayé, ṣugbọn ni opin ọjọ ayé rẹ̀ o ri pe asán ni gbogbo rẹ̀. Ọgbọ́n rẹ̀ ati agbara rẹ̀ ati okiki rẹ̀ tobi pupọ ninu ayé, ṣugbọn ju gbogbo iwọnyi lọ, o mọ pe kò jẹ ère kankan fun eniyan bi o jèrè gbogbo ayé, ki o si sọ ẹmi rẹ̀ nù ati pe kò si ohun ti eniyan le fi ṣe paṣiparọ ẹmi rẹ̀ (Matteu 16:26).

**Igba Ewe ati Igba Ogbó**

Idi kan ti awọn ọ̀dọ́ fi gbọdọ wá Ọlọrun ni ibẹrẹ igbesi-ayé wọn ni pe ki wọn le ṣiṣẹ fun Oluwa ati pe ki wọn le fi agbara igba ewe wọn fun iṣẹ-isin Rẹ̀. Bi eniyan ti n dagba ti o si n di alailagbara, bẹẹni ọwọ rẹ maa bẹrẹ si gbọ̀n-rìrì -- "awọn oluṣọ ile yio warìri"; ara rẹ̀ le ṣe alai dá, ẹ̀yìn rẹ̀ le ti tẹ̀ nitori iṣẹ lile ọ̀pọ ọdun ti o ti ṣe – "awọn ọkunrin alagbara yio tẹri wọn ba," eyín rẹ̀ le ti ká tán – "awọn õlọ̀ yio si dakẹ nitoriti nwọn kò to nkan"; ojú rẹ̀ yoo maa riran baibai, nigba miiran paapaa o le fọ́ -- "awọn ti nwode loju ferese yio ṣu òkunkun." Nigba pupọ o gba pe ki a fi ẹrọ ti o le ran ni lọwọ lati gbọran si eti awọn arugbo lati le gbọran, awò-oju, ọpa itilẹ, ati eyín atọwọdá lati ba le mu wọn bori gbogbo iṣoro wọn (Wo Oniwasu 12:3).

**Lakotan**

Boya aarẹ̀ tilẹ ti mu Sọlomọni ki o to pari iwaasu rẹ̀, tabi boya o n bẹru pe awọn eniyan le bẹ̀rẹ si i sun bi oun ba tun fa iwaasu naa gun pupọ ju bẹẹlọ. Ni opin rẹ̀ o wi pe, "Ninu kikọ iwe pupọ, opin kò si: ati iwe kikà pupọ li ãrẹ̀ ara." Ọna titọ ati ailewu fun awọn ọ̀dọ́ lati rin ni ki wọn ranti Ẹlẹda wọn – ki wọn fi ọkàn wọn fun Ọlọrun ni ẹsẹkẹsẹ ti wọn ba ti mọ pe Ẹmi n pè wọn. kò si ẹni ti o kere ju lati wá Ọlọrun.

Awọn ẹsẹ ti o gbẹyin ninu iwaasu yii yẹ ni kikọ-sori fun ọ̀dọ́mọkunrin ati ọ̀dọ́mọbinrin kọọkan ati olukuluku ọkunrin ati obinrin pẹlu, nitori ninu wọn ni "kọkọrọ" Iye Ainipẹkun wà.

> **"Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o**
> **si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia.**
> **"Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ,**
> **ati olukuluku ohun ikọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu"**
> **(Oniwasu 12:13, 14).**

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni orukọ miran fun Iwe Ekklesiastes?

2 Ki ni a sọ pe igba ọmọde ati igba ọ̀dọ́ jẹ́?

3 Ta ni a ni lati ranti ni igba ewe wa? Ki ni orukọ miiran fun Un?

4 Ki ni a fi dá ara wa ni atetekọṣe?

5 Kọ́ ẹsẹ meji ti o gbẹyin Iwe Oniwaasu sori.

6 Ki ni ṣe ti awọn ọmọde fi gbọdọ wá Ọlọrun nigba ti wọn wà ni ewe?

7 Sọ anfaani mẹwaa ti Onigbagbọ́ ni ti ẹlẹṣẹ kò ni.

8 Ki ni opin igbesi-ayé Onigbagbọ́? Igbesi-ayé ẹlẹṣẹ?

9 Ki ni ṣe ti o fi ṣanfaani fun awọn ọ̀dọ́ lati ranti Ẹlẹda wọn?